# نواقض الإسلام

# Àwọn Nkan Ton Ba Islām jẹ

AR-RISAALAH
RC: 3115259
مكتبة الرسالة
PUBLICATIONS

**Ti Asíwájú Ìpèpè Si Ojú Ọ̀nà Allāh Ash-Shaykh Muḥammad Ọmọ ʿAbdul-Wahhāb Ọmọ Sulayman At-Tamimi— Ki Allāh Kẹ́ Wọn.**

Ni orúkọ Allāh Àjọké Ayé Àṣàkẹ́ Ọ̀run.

Mọ̀ wípé àwọn nkan ti o nba Islām jẹ, jẹ mẹwa

**Alakọkọ**: Ìmú Orogún pẹ̀lú Allāh níbi ìjọsìn fun. Allāh ti o ga jùlọ tó sọ wípé:

﴿إِنَّ ٱللَّهَ لَا يَغْفِرُ أَن يُشْرَكَ بِهِۦ وَيَغْفِرُ مَا دُونَ ذَٰلِكَ لِمَن يَشَآءُ﴾

“dajudaju Allāh kò ní foríji ìmu orogún pẹ̀lú rẹ, a sì má ṣe àforíjìn fun oun ti o ba yàtọ̀ síi fún eni tí o ba fẹ” [Sūrah An-Nisāʾ:48].

Ó tún sọ wípé:

﴿إِنَّهُۥ مَن يُشْرِكْ بِٱللَّهِ فَقَدْ حَرَّمَ ٱللَّهُ عَلَيْهِ ٱلْجَنَّةَ وَمَأْوَىٰهُ ٱلنَّارُ ۖ وَمَا لِلظَّٰلِمِينَ مِنْ أَنصَارٍ﴾

“dajudaju ẹni ti o mu orogún pẹ̀lú Allāh, Al-Jannah ti jẹ èèwọ̀ fun, àti pé iná ni ibùdésí rẹ kòsì ni si alárànse fun àwọn alábòsí” [Sūrah Al-Māʾidah:72].

Lára rẹ̀ ni ìdúran fun oun ti o yàtọ̀ sí Allāh, gẹgẹbi bi ẹni tin dúran fun Alujannu tàbí sàárè.

**Ẹlẹ̀ẹ̀keji**: Ẹni tí o ba gbe àwọn alagata kalẹ̀ láàrin oun àti Allāh, ton képè wọn, ti o sin bèèrè ìṣìpẹ̀ lọwọ wọn, ti o sin gbára lé wọn— ẹni bẹ ti ṣe àìgbàgbọ́ ni àpanupọ̀ àwọn Alfa.

**Ẹlẹ̀ẹ̀kẹta**: Ẹni ti ko ba gba àwọn òṣẹbọ ni Kèfèrí tàbí on ṣe iyèméjì si Kèfèrí wọn, tàbí o gba wípé ojú ọ̀nà wọn da—irúfẹ́ ẹni bẹ, ti ṣe àìgbàgbọ́.

**Ẹlẹ̀ẹ̀kẹrin**: Ẹni tí o ba gbàgbọ́ wipe ìmọ̀nà ti o yàtọ̀ sí ìmọ̀nà ti Anabi ﷺ o pe ju ìmọ̀nà ti Anabi lọ, tàbí ìdájọ́ ẹni tí o yàtọ̀ si Anabi dára ju ti Anabi lọ gẹgẹbi àwọn ti wọn gbọla fun ìdájọ́ àwọn ti wọn ki kọjá ìlà lori ìdájọ́ rẹ—irúfẹ́ ẹni bẹ, jẹ aláìgbàgbọ́.

**Ẹlẹ̀kaarun-un:** Ẹni tí o ba kòrira nkankan ninu nkan ti Anabi ﷺ mu wa, kódà kí ó ma ṣe nkan náà— irufẹ ẹni bẹ ti ṣe àìgbàgbọ́.

**Ẹlẹẹkẹfa:** Ẹni tí o ba ṣe awẹwa pẹ̀lú nkankan ninu ẹ̀sìn Allāh tàbí ẹ̀san rẹ tàbí ìjìyà rẹ— o ti ṣe àìgbàgbọ́. Ẹ̀rí lori eléyìí ni ọ̀rọ̀ Allāh to sọ wipe:

﴿قُلْ أَبِٱللَّهِ وَءَايَٰتِهِۦ وَرَسُولِهِۦ كُنتُمْ تَسْتَهْزِءُونَ ۝ لَا تَعْتَذِرُوا۟ قَدْ كَفَرْتُم بَعْدَ إِيمَٰنِكُمْ ۚ﴾

"sọpé ṣe Allāh àti àwọn ààmì rẹ àti òjíṣẹ́ rẹ lẹ nfi ṣe awẹwa, ẹ ma wa àwíjàre, dajudaju ẹ ti ṣe àìgbàgbọ́ lẹ́yìn ti ẹ ti gbàgbọ́ tẹ́lẹ̀." [Sūrah At-Tawbah:65-66]

**Ẹlẹẹkeje:** Idán— ninu rẹ ni àlúpàyídà àti ìsopọ̀, ẹni to ba ṣe tàbí o yọnu si, ti ṣe àìgbàgbọ́. Ẹ̀rí eléyìí ni ọ̀rọ̀ Allāh tó sọ wipe:

﴿وَمَا يُعَلِّمَانِ مِنْ أَحَدٍ حَتَّىٰ يَقُولَآ إِنَّمَا نَحْنُ فِتْنَةٌ فَلَا تَكْفُرْ ۖ﴾

"àwọn méjèèjì ko ni kọ ẹnikẹ́ni àyàfi ki wọn sọ wipe dajudaju àdánwò ni a jẹ, ma ṣe ṣe àìgbàgbọ́." [Sūrah Al-Baqarah:102]

**Ẹlẹẹkejo:** ìkún àwọn òṣẹbọ lọwọ àti ìràn wọn lọwọ lori àwọn Mùsùlùmí.  Ẹ̀rí eléyìí ni ọ̀rọ̀ Allāh ti o sọ wipe:

﴿وَمَن يَتَوَلَّهُم مِّنكُمْ فَإِنَّهُۥ مِنْهُمْ ۗ إِنَّ ٱللَّهَ لَا يَهْدِى ٱلْقَوْمَ ٱلظَّٰلِمِينَ﴾

"ẹni tí o ba mu wọn ni ààyò àti aláàbò ninu yin ti di ara wọn, dajudaju Allāh o ni fi ọ̀nà mọ ìjọ àwọn alábòsí." [Sūrah Al-Māʾidah:51]

**Ẹlẹẹkẹsan:** Ẹni tí o ba ni ìgbàgbọ́ wipe, ìgbàláyè wa fun àwọn kan láti jáde kúrò ni abẹ́ òfin Anabi Muḥammad ﷺ gẹgẹbi ìgbàláyè ṣe wà fun Khadru láti jáde labẹ òfin Anabi Mūsá عليه السلام iru fẹ ẹni bẹ jẹ aláìgbàgbọ́.

**Elẹẹkẹwa:** ìkọ̀yìn sí ẹ̀sìn Allāh, ì má kọ àbí múulò. Ẹ̀rí eléyìí ni ọ̀rọ̀ Allāh to sọ wipe:

﴿وَمَنْ أَظْلَمُ مِمَّن ذُكِّرَ بِـَٔايَٰتِ رَبِّهِۦ ثُمَّ أَعْرَضَ عَنْهَآ ۚ إِنَّا مِنَ ٱلْمُجْرِمِينَ مُنتَقِمُونَ﴾

“taló fin ṣe àbòsí to ẹni tí wọn ṣe ìrántí àwọn ọ̀rọ̀ àti àmì Olúwa rẹ fun to si gunri kúrò níbẹ̀, dajudaju áa gba ẹ̀san lára àwọn ọ̀daràn.” [Sūrah As-Sajdah:22]

Kòsí ìyàtọ̀ láàrin gbogbo nkan to ba Islām jẹ yii, yálà fun ẹni ti o jẹ aláìní-àkàkún tàbí ẹni to nka nkan kun àti ẹni ton páyà àyàfi ẹni tí wọn bá jẹnípá. Gbogbo eléyìí jẹ ninu àwọn nkan ti o fin burú jùlọ, ni wọn si man ṣẹlẹ̀ lọ́pọ̀ ìgbà.

O tọ fun Mùsùlùmí pe kí o ṣọ́ra níbẹ̀, ki o si páyà fun ẹ̀mí ara rẹ̀. A sádi Allāh kúrò níbi àwọn okùnfà ìbínú rẹ àti ibi ìle koko ìyá rẹ. Ìkẹ́ àti ìgẹ̀ fun Anabi wa Muḥammad àti àwọn ará ilé rẹ àti àwọn Ṣaḥābah rẹ.